COMPLIMENTARY COPY

UNIV. COLL. LIBRARY IBADAN

N ERE TI O DAJU
Polowo Oja re ninu
Irohin Onigbabo
Kowe si
OGA APOLOWO OJA
9, Western Ave,
Suru-Lere.

Irohin
ONIGBAGBỌ

Bolaco Agencies
Onisowo orisirisi ohun elo iwe tite, [illegible] itewe, onte ati ifala. Gbogbo re la ni nikawo,
Wa Wo Ni
BOLACO AGENCIES
6,8 ONIFADE STREET
P O BOX 69
MUSHIN

No. 2 August 18—24 1963 Three Pence

# Bishop Aboyade Cole di Olori

**Gongo yio so ni ile isin African Church Cathedral (Bethel) l'Eko loni ojo kejidin-logun osu nigbati a ba fi Bishop Adeola Aboyade Cole si ipo olori ijo awon African Church**



Aworan oke yi je eyiti a ya nigbati a fi Archbishop ti East Africa Olola Alufe Leonard J. Beecher ni oye Doctor of Divinity ni ilu Gesi, Eniti o wa ni apa osi ni Archbishop ti Canterbury Dr Michael Ramsey.

Bishop na, eniti o je oye alufa ni odun 1925 ni ile Olorun African Salem Ebute metta, di Alufa kikun ni odun ti o tele e si ile Olorun African Bethlehem, Ebute metta, Lehin akitiyan pupo ni idi ise re, awon alase gbe si ipo Archdeacon ipo osu karun odun 1944, lati ibiti o ti de ni Bisop kinni fun agbegbe Ondo ati Warri ni odun 1952.

Lehin osu die, o pada wa si Eko ni odun 1957. Nihin ni owa titi di odun 1960 nigbati ise tun gbe e o si agbegbe Ibadan. Bi osu ti nyi lu osu, ti Ijo si ndagba soke ni a tun ranse pe Bishop Cole lati wa si Eko ni odun 1962. Ko pe lehin eyi ni a dibo yan gege bi olori gbogbo Ijo African.

Nipa ase igbimo African Church ti ase ni ile Olorun Cathedral Bethel l'Eko ni osu karun odun yi, awon alufa ati awon Ijo fenusokan yan Bisop Adeola Aboyade Cole si ipo olori ti yio ni ibujoko re ni Cathedral Bethel l'Eko, ti won si fi se alakoso gbogbo ola, agbara ati anfani ti o wa nidi ipo na loruko Jesu Kristi Oluwa.

O je [illegible] pupo [illegible] pelu owo [illegible] lan.

Bisop Aboyade Cole Alufa kini ti o si se n i Olorun African Cathedra[illegible]

o si dabi eniti a le tokasi gegebi oludasile Ijo African Church. Adura wa pe Oluwa ma sai i to olori ti-n i sona, ki o le sise fun ogo Oluwa nti fuu ire Ijo Kristi laiye yi.



Ipade awon Apostolic pari ni aipe l,eko. Aworan o[illegible]e yi ni eyiti won ya lesi nigbati won pari iPade.

IROHIN
Onigbagbo

Eyi ni tiyin enyin Onigbagbo E ma ka kiesi ma polowo oja yin ninu re.

# Awon Oniwasu oni

## Anglican Churches.

### Cathedral Church Lagos

CATHEDRAL 9 a.m. Rev. J.K. KING 6. 30 p.m.— Rev. Z. O. BANWO

ST. DAVID'S 7. 30 a.m. — HOLY COMMUNION 9 a.m MATTINS MR. O. OSOBA 6. 30 p.m. EVENSONG, THE VICTOR.

ALL SAINTS' YABA 8 a.m. YORUBA MATTINS Mrs. REMI ANEDUN (P) 9.15 a.m. ENGLISH MATTINS Mr. O. ABUBA (P) 6.30 p.m. EVENSONG THE VICAR

## ORO OLOTU

Ki opun yi topari, ni dede osu kejila ni awon ti ognte iwe Irohin Onigbagbo ati People's Monitor yio se ifagagbaga orin kiko larin egbe akorin lati orisirisi sosi.

Eyi ki se akoko se iru ariya bayi. A se iru ere bayi ni odun 1961 ni gbongon Isire Ijoba ni Surulere sugbon a rope ti odun yi yio minringindin ju ti eyi ti o koja lo.

A ni ni ero pe iru ifagagbaga bayi yio mu isiri wa fun gbogbo awon oga akorin lati le rire awon omo egbe akorin tiwon ni o bori.

Ifagagbaga yi ko wa fun C.M.S. tabi Baptist nikan, sugbon o si si gbogbo akorin Ijo patapata.

A ti nri esi lati edo awon egbe akorin ijo diedie, sugbon a nro pe ao ti esi pupo si.

Ki eleku kuluku wa fi agbara orin kiko tire han. A ko ko orin ni ede Yoruba tabi ni Eyinbo.

A nreti yin o.

## AFRICAN CHURCHES

African Salem Morning— Bro J. A. AKINSANYA African Salem Evening— Bro. S. O. AKINYEMI

Jehovah Jireh Suru-lere Morning Rev. O. AJEDITI Evening Bro. E. O. TAIWO

## The Churches of the Lord

ELEGBATA Morning: Elder G. A. FEYISITAN Evening: Mrs A. A. OYELEDUN

SHOMOLU 10. a. m Mr. OLUSANYA 6. p. m. Mr. OLUSANYA.

## Methodist Churches

OLOWOGBOWO 10 a. m. Yoruba Rev. D. O. Babatope 7 p. m. English Rev. M B. Olaniyan

OBUN-EKO 10 a. m. Yoruba Revd. S. A. Akinbo 7 p. m. Yoruba Bro. Akinbo

FANTI 5 p. m. FANTI M. I. Solarin

IKOYI 10 a. m. Yoruba Bro. J. R. A. William. 7p. m English Bro. J. M Caulerick

BESE 10. 30 a. m. Yoruba Oo Alade 5. p. m. Yoruba Bro. Odu

APETU 10. 30. a. m. Yoruba Iro. A Ojo 5. p.m. Yoruba

EKO-OMI 10. a. m. Yoruba Bro. J. M Aina 5p. m. Yoruba Bro. E. A. Fasogbon

OTTA 10. 30. a. m. Yoruba Bro. K. B. Kojele 4. p. m. Yoruba Bro. J. Akinde.

YABA 8. 30. a. m. English Bro. G. H. Walley 10. a. m. Yoruba Rev. E. A. O. Idowu 5. 30. p. m. Yoruba Bro. J. A. Ajayi 7. p. m. English Rev. E. A. O. Idowu

OSHODI 10. a. m. Yoruba Bro. D. A. Famoroti 6. 30. p. m. Yoruba Bro. I. O. Fagbola

ABULE IJESHA 10. a. m Yoruba Mr. C. Thompson 7 p. m. Yoruba Bro. I. B. Odesanya

MEGBON 10. a. m. Yoruba Bro. J. A. Adeyemo 7. p. m. Yoruba Sis. Betty Hands

SHOMOLU 9 a. m. Ibo Bro. Ev ans S

IJU 10. 30. a. m. Yoruba Bro. A. T. Oduyale 4. 30. p. m. Yoruba Sis. A. Cook

ABULE OJA 10. a. m. Yoruba Bro. A. O. Bankole

## METHODIST

WILLIAMS MEMORIAL 8. 30 a. m. English Bro. O. A. Sosina 10. a. m. Yoruba Bro. D. O. Somoye 7 p. m. English Bro. O. A. Fagbohun

MUSHIN 10. a. m. Yoruba Rev. D. O. Babatope 5 p. m. Yoruba Sis. Fasheun

APAPA ELEMU 10 a. m. Bilingual Bro. W. O. Payne 5p. m. Bilingual Bro. E. A. rowojolu

APAPA AJEROMI 10 a. m. Bilingual Bro. O. Coker. 5 p. m. Bilingual Bro. J O Aina

### English

BORNU CRESCENT 10 a. m. Bro. J. G. Cadmo

KIRIKIRI VILLAGE 10 a. m. Bilingual Bro. Jacob

TINUBU 8 30. a. m. Yoruba Mrs. Johnson 10 a. m. English Vic. Davies 7 p. m. English Do

TINUBU 8 30. a. m. Kroo Bro. M. J. Etuk 5 p. m Kroo Bro. V. K. Bamgbala 5 p. m. Togo Bro. O. Somoye



TINUBU METHODIST CHURCH EKO

IKORODU 10. a. m. Re- J. A. Funmilayo 7 p. m Bro. Ogunfile

GBOGBO 10 a Bro ollaja 4 30. p. m Suwadaini C

GBERIGBE 10 a. m. Bro. Ogunsanya 4 30. p. m Bro. A Aina

AGURA 10 a. m. Bro. C. A. Oluwadaini 4 30 Bro Akinyebi

OKE-ELETU 10 a. m. Bro. J Olatunji 4 30 p. m. Do

BAIYEKU 10 a. m. Bro. Adeyemi 4 30 p. m. Do

METHODIST

EWU-ELEPE 10 a. m Bro Eesho 4 . 30 p m DO

EREFUN 10 am Bro Sonoiki 4. 30 p. m Bro Akinbiowu

ST PETER'S CHURCH (FAJI) LAGOS.

9. a m Vicar A O Odukoya

10. a m Choral Commumon in Yoruba Vicar

8. 30. p. m Mr I. O. Adeeiye Vicar

ABEOKUTA CHURCHES

ST PETER'S AKE

9. a m Rev E. O. Akinboro

6. p m Rev M. O Adeniyi

IPORO AKE

10. a m Rev E. O. Folorun

6. p m Evening

FIRST BAPTIST IJAIYE

10. a m Rev E. A. Agboola

6. p m Bro E. A. Sode

ST. JUDES'S IJEUN

9. a m E. Olu Oluyomi

5. p m M. A. Sanyaolu

ST JAME'S IDI-APE

9. am Rev J. A Oluwonmi

6. p. m E. O Ogundirau

AFRICAN CHURCH IGBORE 9. am Revd S. O OPESUSI 7. pm Mr F. O Ekundayo

ANGLICAN CHURCH IKEREKU 9. am Rev E. O Osinowo 7. pm Evensong

ST JUDE'S IKIJA

9. am Mr S O Abiodun

6. pm Mr J A Enilolobo

ST STEPHEN ILUGUN

9. a m Mr M I Osho

6 p. m. Mr. E. O. Ijaduola

OSIELE ANGLICAN

9. am Rev. E. O. Oduwusi

5. pm E. O Odesesan

ILUGUN ORILE

9. am Mr. E. O Oluwunmi

5. pm Mr. E. O Adewunmi

ST PETER'S AKONKO

10 am Mr. J. A Fajebe

5. pm Mr E. O Feyistan

## Sapele Church

WESLEY METHODIST

10 am Major Akinwande

7. pm Major Akinwande

WESLEY HALL BENIN-CITY 10 m. Rev. Bro Eno 5 p.m. Rev. Bros Eno

WARRI SOCIEYT

10 am Rev C O Makinde

6. pm Bro. Taylor

BETHEL BAPTIST SAPELE

9. am Sup S. M. Okpeki

# EWO NI ALAGBAWI?

Lati owo Alufa S. B. Talabi.

A da enia ni aworan Olorun, pelu ihuwasi to pe, oye lati mo oro Olorun ati igboran si ife Re. Eda enia je eyiti ofun u ni anfani lati jiroro pelu Eleda re ti o fee, ti osi n t o j u re. Biotilejepe oje o je aworan Olorun latima ni idapo pelu re, sibe o tidi ona idapo yi pelu Olorun nipa iwa orikunkun ati aigboran si ona ati ife Olorun.

Ogbon ewe ti esu, ati asehinwa buburu tiese nmu wa han gbangba ninu Genesisi 3. Eda farapamo pelu itiju kuro lodo Eleda re, sugbon ona re han si Olorun.

o ni itumo pupo ti a si nlo nipa akitiyan Olorun fun irapada Kristi, araiye. Itumo re di mo ise irapa fi Kristi han gegebi alagbawi toto ti o duro larin Olorun ati enia. Alagbawi toto gbodo je okan na pelu Olorun ati enia.

Ninu Majemu ti lailai, Olorun nba enia soro lati e n u awon Woli, sugbon ninu Majemu tit un, Olorun nba wa soro lati odo Jesu Kristi. Olorun nsoro lati enu omo Re eniti ise aworan ogo Re ati e da Re. Baba ni Olorun, Kristi si ni omo. Idagbasoke Kristi je on ti o daju. On ni o to fun ise alagbawi larin orun on aiye. Paulu ninu Episteli se ayewo ise Alufa Aaron ti o se fun igba die yato si ti Jesu Kristi ti o je ti aiyeraiye.

Nitorina, alagbawi kansoso na nilati je O m o Olorun.



Alufa S. B. Talabi, Eniti o nse alabojuto ile isin St. Peters Faji L'Eko.

> **Ojo Isimi Kewa lehin Metalokan**
>
> **ADURA**
>
> OLUWA, je ki eti anu re sisi adura awon iranse re onirele; ati ki nwon ki o le ri ibere won gba, mu won bere irohin ti yio man wu o, nitori Jesz Kristi Oluwa wa. Amin.



Eyi ni aworan ile Olorun tiowa ni i₁u Issele Uku ni iha iwo orun

Otito kan wa ninu irapada t i Olorun. Genesisi 3 : 9 fi otito yi han bi Olorun se nwa enia ti o lumo 'sinu ese. "Olorun si ke pe okunrin na, o si wi fun pe, nibo ni iwo wa? On si wipe, mo gbohun re re ninu egba, eru si bami, nitoriti mo wa ni ihoho, mo si farapamo" Bayi ni eda beresi sako lo titi di igbati Olorun pe Israeli ti o si ko won gegebi enia re lati se eleri re ni gbogbo agbaiye.

A tun ri ife irapada ti Olorun nipa yiyan ati pipe ti o pe Abrahan, ati gbogbo awon majemu ti o ba on ati awon iran re da, nipa eyiti o n a fi si sile fun bibo ati ise ti Jesu Kristi.

## Olorun Yio se gba enia re la?

Enia re ni won, o si ba won da majemu. Nitorina, bi o se fi ife yan won, ko ni ya wa lenu pe yio fe igbala won. Nigbamiran a dabi enipe Olorun sa won elomiran nro pe Olorun ngba enia ti njiya la bi oluware ronupiwada. Olorun ngba enia la nitoripe won je oloto. Iwe Isiah 53 fi ipo Jesu han gegebi alagbawi. Awon o r o miran ninu Majemu titun Bibeli tun ntumo ise Kristi bi ti alagbawi ati onilaja.

## Irapada

Itumo Irapada ni mimu ore ati ibalopo pada bo pada bo s i p o lehin ija. Nipa iru bibo sipo yi, enia tabi ohunkohun nyipada lati bo si ona ti oto. Nipa Iku Kristi ipo ti enia wa si Olorun ti yipada. A ra enia pada sodo enia. Iru irapada yi mu igbala wa fun eda to ti sako lo. Nipa irapada ti iku Kriti mu wa sinu aiye, iyipada Olorun ko oju anu si enia.

Ise Kristi ni ile aiye mu ki Olorun sunmo awon eni ti o sonu. Olorun faramo Ise Kristi, nipa bayi o duro gegebi oludariji enikeni ti o ba gba Kristi gegebi Olurapada. Nigbati okan enikan ba mo riri iku Kristi fun ese, yio gba okan re la, gbogbo aifeni yio kuro, ife ati ibalopo yio si wa.

## IGBALA

Igbala je koko oro ti da Kristi, ohun ti o san fun Igbala eda, ati asehinwa ise Olorun. Kristi ni olugbala eda, a yan a pelu a s e. Igbala ti o nfihan ki se tiife ti omo nikan, sugbon p e l u ti baba ni. Emi mimo papa nsise iyanu nipa ona igbala.

Pelu Aposteli mimo so pe, "A ti ra nyin ni owo iyebiye Gbogbo owoiyebiye yi tun nfihan pe Olorun ko le foju fo ese eda, ki o si da yin sile, ki a to le gba otiio Olorun, a nilati san nkan fun igbala wa, eyi ti ise ebo Kristi papa. Eyi ni ebo nla ti Kristi san nitori wa. "Ninu Ihinrere Mark 10 : 45 a tun ka bayi, "O fi ara re sile lati ku dipo awa, lati ku ki awa le ye."

## EBE.

Igbesi aiye Kristi kun fun ebe ati ebo. Eleyi farahan ninu iku oro ti o ku. Iku re je nyanmo. Bi ibinu Olorun si ese ti han ninu iku Kristi, bena ni ife re han si awon elese.

Lakota.. ninu Episteli si awon Heberu, Paulu

# Orin Wa Oni

Ori[n] yi je eyiti a nko lati ba Oluwa soro ati lati ya nkan si mimo.

Eniti o ko rin na ni Charlotte Elet ti a bi sinu rogbodiyan awon Faranse ni Odun 1789 ni ileto kan ti a npe ni Clapham.

Ileto yi lokiki fun pe ki a bi awon enia jankanjankan sibe. Charlotte tio je eniti o fi ara re fun isin Olorun ku ni odun 1871.

JOHN 6. 37.

1\. p Bi mo ti ri—laisawawi
Ohun kan lehin eje Re,
B' O si tipe mi pe ki nwa,
cr Olugbala, mo de!

2\. p Bi mo ti ri—laiduro pe,
Mo fe ki ekan mi mo toto,
S' odo Re t' o le we mi mo,
cr Olugbala, mo de!

3\. p Bi mo ti ri — b' o tile je
Ija lode, ija ninu,
Eru lode, eru ninu,
cr Olugbala, mo de!

4\. p Bi mo ti ri — osi, are,
Mosi nwa imularada,
Iwo l' ole s' awo'an mi,
cr Olugbala, mo de!

5\. mf Bi mo ti ri — 'Wo o gba mi,
'Wo o gba mi towotese;
cr N'tori mo gba 'leri Re gbo,
Olugbala, mo de!

6\. p Bi mo ti ri —ife Tire,
cr L' o sete mi patapata -
f Mo di tire, Tire nikan,
Olugbala, mo de!

7\. mf Bi mo ti ri, ki mba le
cr B' or' — ofe Re titobi to,
f Laiye nihin, loke lohun,
Olugbala, mo de!

# Bawo ni Isoji se de Ilu Eko

Ni ojo kewa osu keje odun yi ni gbogbo ile Isin Olorun L'eko nro keke fun imurasile ajodun adota odun ti a da Isin Isoji sile ni Eko. Lehin ipade ojo mokanla, awon onigbagbo se Isin idupe kan lati fi kadi ipade na. Gbogbo eto na larinrin pupo. Alaga ipade Isoji, Ólola Dokita J. Olumide Lucas O.B.E. pelu awon ti o se eto na.

opitan ... so pe Ipade Isoji (Keswick)— Convention) bere ni Ile Olorun Holy Trinity, Ebute Eko. Gegebi a ti gbo Ile Olorun yi je okan ninu awon ti o kereju lo ni Ilu Eko. Ile sugbon elesin Kristi ti njeri Jesu Kristi nipa aiye be.

AKOLE

Gegebi a ti gbo, idi re ti a da Ipade Isoji sile ni ile wa ni lati wa isokan gbogbo elesin Kristi.

awon ipade Isoji lati s to won ni Ile Iwa Aroloye itoriti aye yio wa fun olukuluku lati joko. Ni odun 1917, Ile Isin Olowogbowo Methodist ni a ti se Isin na lati je ipe



Eyi ni Aworan awon Alufa gbogbo Ijo ti o se to Ipade Isoji ti a se lodun die sehin.

Sugbon igbawo gan ni ada Isoji sile l'eko? Tani o da a sile? Kini idi re ti a fi da a sile?

IDASILE

Ni osu kewa odun 1912 ni Alagba Alufa Toomas Jacobson Adesina Ogunbiyi da Ipade Isoji sile ni Eko. Saju idasile yi, nigbati o lo si iru Ipade yi ti a se ni Keswick, ile Gesi, okan re gbina lati ri iru iranlowo ti emi nse lara awon ti nlo si ipade na. O daa loju pe iru eto fun nkan bayi yio mu awon enia wa lokan. Igbagbo re nigbana ni pe Olorun nran on lati mu iru anfani yi wa sarin awon elesin Kristi ni Nigeria.

ISOJI NI EKO

Alufa T. A. J. Ogunbiyi pada si Eko pelu okan kan. Lehin ti o ti pari gbogbo eto ni Ile Gesi; o da Ipade Isoji Ekai sile ni Eko. Bayi ni oro yi "Keswick" ti a tunmo si ISOJI se de Eko pelu gbogbo awon asa wonni ti a mo pelu re ni Ile Gesi. Lehin igba die, Alufa (Canon) Claude Worsey-Wakeman eniti o ni oye nipa ajo Isoji ti Ile Gesi, darapo pelu eto Alufa Ogunbiyi, a si yan gegebi Alaga Egbe na. O wa ni ipo yi titi di ojo iku re ni odun 1945. Awon Olorun na ko le gba ju adotalerugba enia lo, sibesibe nibe lati bere Ipade ni osu kewa odun 1912, ti won si npe ose na ni "Ose Isoji."

Idi pataki ti a fi da Ipade Isoji sile ni Ile Gesi ni a gbe jade nigbati Ipade na bere ni odun 1875 ni ile na. Iru ipinnu won nipa dida a sile na ni Ipade Isoji ti Eko gba ti won si nlele e. Ipinnu na ni lati mu igbesi aiye awon elesin Kristi nipa ti Emi duro sinsin, lati mu awon elesin na sunmo Olorun fun emi akotun ati fun idaniloju toto pe ona ore-ofe ko se, ati gbigba agbara pataki fun lilo iru igbesi aiye olu- Akole Ipade Isoji ti Ile Gesi, ti awa na si gba ni "Okan ninu Kristi Jesu"

IDAGBASOKE ISOJI

Eniti o ti nkiyesi gbogbo eto Isoji so fun mi pe Ipade Isni na dagba larin odun die ti o fi je pe ile Olorun Ebute Ero ko le gba awon ti nwa si Ipade. Ife Alufa Ogunbiyi eniti o da Isoji sile ni pe ki a fi Ebute Ero se ijoko Ipade sugbon eleyi ko be. Ni odun 1915, Alufa (ti o di Bishobu lehinna) Adolphus Williamson Howells ti o je Alufa ni Ile Olorun St. John's, Aroloya nigbana ro Alakoso ibe, Alufa Evans E. Williams.

ISIN OPE

Loni yi, ipade Isoji ni ilu Eko ti gbe adota odun sehin, ipade na si nie siwaju. Eyi ni o mu ti awon nigbagbo se Isin Ope ti o larinrin ni orisirisi ile Olorun "Protestant" ni Ilu Eko ni ojo Isimi kokanlelogun osu yi. Ni ile Olorun St. Pauls' Breadfruit, leko ogoro enia lo fi towotowo josin lati dupe lowo fun iranlowo re atehinwa. Eniti o wasu ni Dokita

WO OJU IWE 5

# Ibeji: NJE O TONA KI IYA RE SAGBE



Awon Yoruba ma nso pe Kehinde ju Taiwo lo, sugbon awon eya miran ni ero ti o yato gedegbe si eyi. Ni temi, nko faramo opolopo awon omo ile Yoruba ti won lodi si ero yi nitoripe Taiwo ni a bi saiyesaju Kehinde.

Awon omo meji ti iya kan ba bi ni ikunje ekan botilejepe alafo wakati die wa larin ibi won, ni a npe ni ibeji. Asa Yoruba gbe agba fun abikehin ninu won. Awon ibeji miran ma njora, wiwo oju won le ri bakanna. Bena ni a si ri awon miran ti ko jo ara won rara. Nigbamiran ibeji le je okunrin ati obirin eyi okunrin le jo baba re, ki obinrin sidabi iya re.

Awon eya miran korira ibeji tobe ti won fi npa won. O je oliun rere pe awon Yoruba feran ibeji; Nwon gbagbo pe Orire ni fun idile won.

Elomiran tile nwipe ibeji okunrin meji yio so ojoaiye baba di kukuru. bakanna ni ti ibeji obinrin meji yio mu iru re ba iya re. Eyi a le je atito? Nko faramo o, nko si le gbagbo. Nwon tile wipe ibeji je iran awon inaki ti nfo lati ori igi kan de ekeji ninu igbo.

Awon ole obi ti ko si loye ma nyagan ninu sisaghe fun ebun. Awon mii nso pe ibeji lo kan a ni ipa fun won lati ma jo ati lati sagbe. Sagbon di won ko se se eyi ni arin ile won. Ibeji se le tari won si iru nkan yi.

Emi gbagbo pe funra awon obi ni won nse iye nitoripe won yole. Iya ibeji ti nsise ni le ise tabi ile itaja ko le riaye fun nkan wonyi, melomelo ni onisowo ti o ni oja loti ta. Mo ti ri opolopo awon ibeji ti won wa laiye bi-otijepe obi won ko sagbe.

Kini enyin onkawe ri so si?

Pambotoriboto Mogb omojo. Iya ibeji ni yen o

**Isoji,**

[illegible] B.D. Alagba [illegible] ti Methodist Alufa [illegible] B.A., B.D., Alakoso Ijo ti Angcan leko, Alagba Dokita J.T. Ayorinde M.A. D.D. Akowe agba fun Igbimo Baptist, ati Alufa J.F. Akinrele M.A. ti o ti fi gbakan je oga Ile Eko Giga awon odomokunrin Ondo wasu nibomiran.

# Irohin Kakiri Ile Olorun

## ALADURA NSAJODUN TABORA

Awon egbe Aladura ti church of the Lord jake jado gbogbo agbaiye bere ajodun awe ni Sojo isinmi ti o koja. Ojo mejila ni won o fi gba awe na, eyi ni yio si je ajodun ogun ti won ti nse.

Woli ti o nbojuto eka ile Olorun yi ni Apongbon l'Eko lo fi eyi ye ni, o si tun se afikun pe ojo kejilelogun osu yi je ojo ti a ya soto fun gigun oke Tabora ni Ogere ni agbegbe Ijebu Remo labe akoso Alagba Dokita J.O. Oshintelu.

## EGBE ODO SE AJODUN

Ni ose ti o koja lo ni ile isin Kings Church Enuowa ni agbo pe awon egbe odo (Anglican Youth Fellowship) se ajodun idasile egbe won.

Gbogbo awon egbe odo ti ijo C.M.S. ilu Eko ni o si pese si ibi ajodun na lati ba won yayo.

Ninu iwasu re, alufa EA Babalola gba won ni iyanju, o si fi ye won pe awon odo ni Opomulero nitorina won nilati ji giri si ise nla ti o wa ni waju won.

Lehin isin awon egbe odo ko ara won lenujo.

## Smith Pada S'Eko

Alufa ti nbojuto awon odo Ijo Anglican ni ekun Eko ti kan sara si awon odo ile Nigeria fun ife won si ise Olorun.

Alufa Smith nsoro yi fun onirohin wa kan lehin ti o ti pada de si Eko lati Oyo nitibi o ti ko ede Yoruba.

O tenumo pe o to, osi ye fun awon odo lati fi tokantokan ko nipa irapada ti onigbagbo. n O nba oro re lo bayi, Onigbagbo toto kise eyiti a bi sinu re sugbon eyiti a tun bi nipa ipade ti emi pelu Kristi. Gegebi oro re, awon odo ile Afrika mo Olorun ju awon Oyinbo lo. Sugbon o se ikilo nipa ewu ti o nbe niwaju won. O gba awonmode ile Nigeria lati k'eko nipa isubu ti awon Oyinbo, ki nwon si tiraka lati wa ni pipe.

## Ile Olorun Ife da aso titun fun Akorin

Awon aso titun fun Egbe Akorin ti Ile Olorun St. Phillps Aiyetoro Ile Ife ni a gbo pe a ti owo Alakoso Ijo na ya si mimo nibi isin alarinrin kan ti a se ni aipe yi.

O ju wakati kan ti a fi se isin na, ogunlogo enia lo si pejo sibe lati ekun Ife.

Ile Olorun St. Phillips ni a koko da sile ni ekun Ile Ife.



Aworan oke yi ni ti omo egbe akorin ijo St Stephen ni Kano.

## SERAFU SE AJODUN IKORE

Agbo pe won se ajodun ikore ti o larinrin ni ile Olorun ti awon Kerubu ati Serafu ti owa ni 10 Hotowu St. ni Eko ni ose ti o koja.

Ajodun na dun to be ge ti ojepe awon ero ti owa sibe fere male ri aye joko si. Biotilejepe ojo nro bi ina ni ojo na, ese kogbeji ni adugbo ibe ti gbogbo ibe si ndun yungba.

Baba Aladura, oga ijo won papa so pe o ya on lenu pe ajodun na le dun to be.

Ki Olorun jeki ari opo odun o, Amin.

## Irohín ni Soki

"IJO C.M.S. YAN AKOWE FUN AFRICA"

Igbimo Ijo Church Missionary Society ti yan Alufa Brian J.H. de Saram gegebi Akowe re fun Ile Africa on yio gba ipo Canon J. V. Taylor ti a fi se Akoweagba CMS nisisiyi.

Ehi adota odun ni Alufa Saram. A bi i ni ilu Kanni Ceylon, o si ko eko ni ilu Eko giga Dulwich London ati ni Royal College of Sciene nibiti o ti gba oye B.Sc. Tele ri, o ti nsise gegebi Akowe awon omokunrin ti o fe wo ijo C.M.S.

## Zebra House

Igbimo ti nje Zebra House sese si ile ero kan ni Ilu Camden, London fun awon akeko ajeji tio ti gbeyawo Ile ero na tinje Impala House pin si ona meji sugbon oke mokanla ni gbogbo won

Gegebi a ti gbo igbimo Zebra House je egbe ti o tikarare nwa ona lati ko orisirisi enia jo ni irepo. Lara nwon idile ti o ngbe ile na nisisiyi ni a ti ri awon enia lati Nigeria, Ugauda, Tanganyika, Kenya, India, ati Sudan.

## Ijo Iwaya Se Ikore

Ogunlogo awon onigbagbo ni o pejo si ile Isin Saint Francis (Anglican) Church, Iwaya leba Ilu Eko ni owuro ojo Isimi to kojayi lati se ajodun Ikore

Isin na ti Alufa Alabojuto Ijo Alufa A. O. Ayodele D. T. H. se ni ede Yoruba dun pupo.

Awon egbe akorin ti a yan funajodun na korin aladun ti, a fi ilu Yoruba ati duru gb lese.

Ninu oro iyanju re Alufa Ayodele toka awon odo si Iwe Owe 1: 10 nibi ti eniti o ... iyanju lati ko ehin eti so ipe awon elese. O la gbogbo ona ti esu le gba tan omode, o si awon odomode lati ma sora ti won ma si subu si ikekun oludanwo.

Alufa Ayodele so fun onirohin wa pe awon enia Ijo Iwaya nsa ipa won ninu Ise Oluwa.

## Lambeth da ol ori Ijo Ila Orun Africa l'ola.

Olori Ijo (Anglian) ti Centerburi, Dokita Michael Ramsey ti fi oye ojogbon Lambeth ninu oro Olorun da olori Ijo Ila-Orun S. Africa, A. J. Leonard Beecher lola nibi eto kan ti a se ni afin Lambeth, ni Ilu London laipe yi.

Omo ilu London ni Dokita Beecher, osi ti sise fun odun marunlelogbon gegebi olukoni, ajihinrere, olutunu ati oselu ni ile Africa. A fi je olori Ijo (Archbishop ti Ila orun) Africa ni odun meji sehin ti otije Bishop ile Mombasa. Gegebi amoye ede orisirisi, osa ipa lati te iwe itumo ede Kikuyu.

Aworan oke yi ni yi Dokita Michael Ramse- (lapa osi) ati Dokita Beacher (lotun) nibi asey: net

## IJO WESLEY IKOYI

Alufa M. B. Olaniyan ti owa ni ijo Methodist ni Ikoyi ti ye onirohin wa pe won yio se isin imole ni Ale.

Eniti yio se idari eto na ni Alabojuto Alufa A.S. Solarin, alaga igbimo Methodist ni Eko.

Ohun pataki ti yio je ara nibi isin na ni pe, kaka ki won tan ina Lentiriki, abela ni won yio tan.

SE O FE TE IWE IKORE

TABI IWE MIRAN

jeki

CRUSADERS PRESS LTD.

te won fun e

KOWE SI OGA ISE

9, WESTERN AVENUE, SURULERE

# OBINRIN KAN BI INAKI

ILU Benin rokeke lose to koja nigbati irohin tan kale pe omobinrin kan bi Inaki ni ile ibimo Anglican. Gere ti o bimo na tan ni a gbo pe o daku, ti awon oluto ile ibimo na si bere si se 'ajo re. A gbo pe Dokita Nakpade sise abe fun u ki ara re to bale.

Sugbon bi a ti nse ajo re, ni ogunlogo enia da wo inu ogba ti wan si kgun ferese lati foju ganni omo ina'i na. logan, awon oluto ile ibimo na ranse si oko obinrin na lati wa gbe omo na, won si le awon enia na jade.



Omo ni ini Oluwa, Beni oni Psalmu wi. Aworan ti e nwo loke yi ni ti Alufa Agba Jones ti o ti fi gbakan je Olori Ijo Methodst ni ile yi nibi Isomoloruko kan. Ire a kari o.

## OMOKURIN KAN KU S_GBE ONO

Awon olopa Benin nsakitiyan lati mo ohun ti o fa iku odomokunrin kan ti a ba oku re ni opopo ti lo si ona Sapele lati Benin. Ki a to gbe oku re lo si ile alarun fun iyewo, awon olopa ri iboa ilewo ati ota die lapo re won si tun ri keke kan leba, odo re. Gbogbo awon enia ti ngbe tosi ibe ni awon olopa ti fi ogbon wadi oro won ENE-ORA

## Abiyamo ku lojo ikomojade

Jinjinni dabo awon ara Eme-Ora ni agbegbe ilu Benin nigbati omobinrin subu lule bi a ti nkii ku omo, ti o si ku. Oko obinrin na, Ogbeni Esezobor ni a gbo pe bi o ti nmura lati ko omokunrin ti iyawo re sese bi jade, ti o si ngba awon ara adugbo. ti o wa ki won ku ewu omo lalejo ni iyawo re so fun pe inu on ko fara ro. Iyawo na mu egbogi oyinbo, sugbo lesekese o subu lule, o si ku.

Obinrin na, Aikohi ti o je akikanju ninu egbe awon odo ti ilu Eme ni a sin ni Ile Olorun St. Joseph Catholic Church, Eme ni ojo simi to koja. Omo meta ni o bi.

## Ode Pa Erin Ni Eme-Ora

EME-ORA Bakanna ni a gbo lati Eme-Ora pe awon ara ilu ibe tu sode ti won [illegible] tese rin mile me- [illegible] erin nla kan ti ode kan pa ni ojo [illegible]osu yi. [illegible] bi [illegible] a gbo, erin na tobi to tons meji ati Poundi medogun.

Ode na, Ogbeni Izegagbe so pe eyi ni igba keta ti on pa erin.

## ALUFA OBIRIN

LERINKEJI a gbo pe a tun ti fi obirin kan joye alufa ni ilu Norway.

A si gbo pe awon alase ti fi ase si ifijoye re sugbon Bishopu Oslo ni Johanes Smeno si nko lati se isin ifijoye na.

Alufa obirin na ni Agnes Vold eni odun Mokanleladota.

## IJO PRESBYTERIAN SE IPADE NLA

NI ipade awon Methodist ti won se ni Ireland gba pe ki won pe ipade nla ti awon Presbyterian Churches lati le jiroro lori oro irepo ti won fe so ni Ireland.

Alufa P. E. Hill ni o fi eleyi ye onirohin wa kan nigbati o nba soro lori ifowosowo ninu ise Oluwa.

## 130 Aposteli Pada si Ife

LAIPE yi ni a gbo pe awon ijo Aposteli ti o lo si Eko fun ipade nla pada si Ife.

Lati ki awon ti o lo kabo, gbogbo ijo Aposteli se isin pataki ni ile isin won.

Lala awon sosi ti o sesin ni Apostolic ti modakeke, Oke Isoda Ilare.

Eniti o wasu ni ijo ti Ilare ni Alufa Dagunduro

Ti enia ba gbo orin ti awon akorin na nko, nse ni yio fi ijo be e.

Ninu iwasu re ti o mu lati inu St, Mathew 25, o so fun wa bi a ti se le mura fun bibo Jesu Kristi O si tun gba wa niyanju lati ma wasu ihinrere fun alaiye.

## ALUFA PARKER DE

ENITI oti je bi oluko agba ni ile-iwe Igbobi College Yaba ti de si ile Naijiria fun ibewo kekere.

Onirohin wa kan so pe nigbati on bere ohun ti o wa se nse ni won so pe awon kole so, sugbon won rope owa niwa ti ore ni.

A gbo pe yio se iwasu ni ile isin Cathedral Church Lagos.

## Irohin Onigbagbo Gbayi

IROHIN ko to afojuba, eniti o ba debe lo lo so.

O di kirakira ni Ile-Ife ni ose ti o koja lati ra Irohin Onigbagbo.

Kise? Ara Ile-Ife ma nife si Eleda won o. Ki Oluwa tubo ma fi Emi Re bo yin o. Amin.

Onirohin wa so pe riri ti won ri iwe irohin yi lasan, nse ni won nyin Oluwa logo ti won si nkorin mimo.

KERE O

LO SE TOMBO E O RI

IROHIN ALADUN ATI AWON A ITAN ORISIRISI NINU

IROHIN ONIGBAGBO

TETE RA TIE

Iwe yi [illegible] 9 Western Avenue Suru-Lere Olotu S O Sangosina 8 Ajoke Dosunmu St Surulere